# OBA AKINSANYA JERI AWON ACTION GROUP


# IROHIN YORUBA

Ęsin Oro Wa— "IWAJU L'OPA ĘBITI NRE SI"


**Akiyesi**

A fę ki awon onibara wa ma san owo si apo wa dede, ęniti ko ba san owo tirę, ki o ma ya a lęnu bi a ba da a duro lojiji, a o si gba owo wa lowo rę

OLOTU
IROHIN YORUBA

ISIN IRANTI AWON TOKU SOGUN : ROBERT NWANNA (ELERI-ES ) KU SOJU IJA


VOL. IV NO. 69. IBADAN, MONDAY, NOVEMBER 19 1951, OWO IWE IROHIN YORUBA — KOBO KAN (1d)


## Isin Iranti Awon T'oku S'ogun

Ni ojo Aiku ti işe ojo kokanla oşu yi ni Ijoba şe isin iranti awon ti o ti ku si ogun ni Ile Isin Cathedral Church of Christ. Ęniti o si şe alakoso isin iranti na ni Ęni-owo julo Bişopu agba Lokita L.G. Vining. (Archbishop of West Africa)

Awon ti o wa si ibi isin iranti na ni awon ogu pataki ninu işę-oba, awon Aşoju ninu Igbimo Aşofin Nigeria, Mayor Eko ati awon Aşoju Igbimo Munisipa Eko. awon Ologun oju-omi ati ti ori-ilę pęlu awon ęgbę ologun ti nwon ti kuro lęnu işę ogun-jija.

Bi Adele-Gomina Ogbęni E A J Benson pęlu ogagun Ogbęni H A Parker ti oko ogun "Bermuda" ti o şęşę gunlę si Eko nislaiyi ati Iriju-Gomina (A.D.C.), Ogbęni John Purple ti de ni Bişopu agba na ba si mu won lo si aye ti a ti pese silę de won.

Adele-Gomina ni o ka ęko pataki ti a yan fun ojo na. Bişopu agba na ni o si şe iwasu pataki lori iranti awon ti o ti fi ęmi won lelę fun awa ti a wa laye ki a le ni alafia a ti gbe ile aiye. Nwon si şe adura pataki fun ęmi awon ti o b'ogun ja ti nwon si b'ogun lo na.

Lęhin isin ni nwon wa lo pari gbogbo eto yoku ni ibi Şoja-Idumota (Cenotaph). Gbogbo awon Oloye ni arin Oyinbo ati enia dudu ni o wa fi ododo-iranti (Wreath) si ibę fun apęrę işę rere ti nwon şe fun ilu wa nipa titu ęję won silę.



Oba Alaiyeluwa Samuel Akinsanya, Odęmo Ishara, de si Eko ni ojo kejila oşu yi o si ba Ęgbę Afęnifęre (Action Group) şe ipade ti nwon şe ni adugbo Amuto. O si ję okan ninu awon ti o şe alaye fun awon ara Eko ninu ipade yi, iru işę ribiribi ti awon Ęgbę yi ti şe ati eyiti nwon tun ngbero lati şe fun anfani ilu wa ti nwon ba pese sinu Ajo-Igbimo Titun (Western House of Assembly) si nwon nbere ibo awon ara Eko fun yi.

O si tun la a ye awon enia ti o pejo sibi ipade na, orişirişi ifasęhin ti yio wa fun orilę-ede wa ti a ba le fun awon Asoju Ęgbę N.C.N.C. laye a ti ni ijoko pupo ninu Igbimo na.

## Robert Nwanna Ku S'oju Ija

Ni ojo 'Ru ti işę ojó koje oşu yi ni odomode-kunrin kan omo odun mejilelogun pere ti o nje Robert O Nwanna, şugbon ti gbogbo enia mo ni Battling Roberts' nibi ere ęşę jija ni o ku si oju-ija. Ni Gbongan Apejo Glover Memorial Hall l'Ębiogbęti.

Ógbęni "Battling Roberts yi pęlu "Blackie Power" ni o bęrę ere ęşę-jija ti gbogbo enia si ngbadun awon ab'ęşę ku bi ojo na. Şugbon lairotęlę ni Battling Roberts lule o si daku rongbondon, "ere ni aşaya ni" ni awon ba fi gbe e lo si Ile Iwosan (General Hospital)

Anu şe gbogbo enia lati gbo ni ojo keji pe odomodekunrin yi fi bę ę ku bambam. Eyi ni igba akoko ti iru nkan bayi o ko şęlę ni arin awon alere ęşę jija ni ilę yi (Nigeria) Bayi ni Battling Roberts şe ku si oju Ija o. Ki Oluwa fi oran mo bę e fun awon ębi rę ati awon ęlęgbę rę.

### ENIA MĘRIN DI AŞOJU ILU

IGBIMÓ EKITI—Ni ojo Kętala oşu kejo odun yi (13. 8. 51), ni gbogbo enia lomode lagba onile ati alejo ko ara won jo si Awofin Oba-Igbimo lati dibo fun awon ti yio ję Aşoju won ninu Igbimo ti gbogbo Ekiti, Enia mejila ni Ilu yan lati dibo fun, şugbon awon męrin ni Ibo na mu. Inu gbogbo ara ilu si dun si awon męrin na

Nitoripe ko si ęniti o ni Ikun sinu si won, oruko awon męrin na ni Olori D. Akinsayo (Oloja Orun) Ogbęni G K Ogundahunsi, Abraham Akinwamide ati Jimoh Balogun.

Adura wa ni pe ki Olorun maa to won si ona rere ki Ilu si le ma a ni ilosiwaju ni akoko ti won Amin

Aba nyin yo o ęnyin Aşoju wa

### OKUN GBE OPOLÓPO ILE LO

EKO—Anu şe ni lopolopo lati rohin ohun ti oju awon ti o ngbe eti Okun (Victoria Beach) ri ni afęmojumó ojó Aiku ti işe ojo kokanla oşu yi, nipa ti omi okun ti o ru wuya ti o si ko opolopó ile won lo.

Awon ti omi Okun yi so di alaini ile lori moto ogorun enia. Opolopo ohun ini won ni o segbe sinu ikun-omi yi. Şugbon a dupę lowo Olorun po ęmi enia kan ko şegbe sinu ikun-omi na.


SMOKED HERRINGS
We offer Superior quality
NORWEGIAN SMOKED
HERRINGS
Hard Cured, in boxes containing 18lbs Nett. weight. (60 to 80 Herrings per box) at Nett C.I.F. price of only 16/6d per box in lots of 120 boxes for £99 or Sample lots of 60 boxes for £51,
Cash with order.
SEND ORDER AND CASH NOW
QUILLIAM PRODUCTS,
16, Waldegrave Park, Twickenham
Middlesex, ENGLAND.



Ę maa ka iwe
**Irohin Yoruba**
olgbagbogbo fun orişiriş irohin.


## Akiyesi Pataki

Ipade Alufa Bolaji Akewukewe ati Evangelist Akande ni ilu Ogbomosho lati owo Alfa S Bolaji Akewukewe yio bęrę si jade ninu iwe wa ti osę ti mbo. Şe ę ti gbo ti Evangelist Akande, ki ę si tun gbo ti Alfa Bolaji dele ki ę le mo eyiti ę o so si oro won na dada,

OLOTU

OWE:— BI ERIN BA JE TI KO BA YO IGBE NI OJU O TI.

# IKEDE IJOBA

APA-BIBU FUN ARUN IBA-PỌNJU PỌNJU ATI ILẸẸ-GBONA
(FUN AWỌN TI O BA FẸ WỌ ỌKỌ OFURUFU LỌ SI IDALẸ
Yellow Fever and Smallpox Vaccinations and other Inoculations for persons intending to travel by Air.)

Awọn ti o ba fẹ wọ ọkọ ofurufu kuro ni ilẹ yi (Nigeria) lọ si idalẹ ni lati ni Iwe-ẹri apa bibu (Internation Certificates of Vaccination) ti o daju fun ti Iba pọnju-pọnju ati ti Ilẹẹgbona lọwọ

ARUN IBA PỌNJU-PỌNJU (YELLOW FEVER)

Ti o ba ṣe pe AKỌKỌ bu apa fun Iba pọnju-pọnju ni awọn ero idalẹ na ko gbọdọ ti i kuro ni Nigeria titi ọjọ mẹwa yio fi kọja lẹhin ti nwọn ba ti bu apa tan. Awọn ti o ba ṣepe nwọn tun bu apa fun ni ekeji ni le ma a lọ lẹhin ti nwọn ba ti bu u tan, ti a ba ti ri ẹri ti o daju han Bupabupa (Inoculating Officer) na pe akoko ti nwọn ti bu ti akọkọ koi ti kọja ọdun mẹrin ni o, ki o si tẹ ẹ lọrun pe Iwe ẹri atunbu-apa ni gan an.

Ni ibi pataki ni a le fi aye apa bibu fun Iba pọnjupọnju yi si, ki o le din iyọnu a nwọkọ kakiri ku ati ki awọn ohun elo rẹ le bọ si arọwọto, ki iṣẹ paapa sile rọrun ni ṣiṣe.

Ibi ti aye apa-bibu na wa ni :— Eko, Kano, Zaria Jos, Kaduna, Yola, Maiduguri, Ṣokoto, Gusau, Ilọrin. Minna, Ibadan Port Harcourt. Enugu, Warri, Calabar, Forcados, Victoria.

Apa bibu (Yellow Fever Inoculations) ti awọn enia ti o ba wa ni Eko yio jẹ lati ọdọ Pathology Department Broad Street, Lagos, ni agogo mẹsan Ararọ Satide. Awọn ti o si le ri aye apa bibu na ni awọn ti o ba ti ṣe eto rẹ tẹlẹ pelu Pathologist Lagos nipa iwe kikọ tabi ki o tẹlifonu (Tel. Lagos 332) o pẹ patapata ni ọjọ kan (24hours) ṣaju akoko ibupa na.

## ILẸẸGBONA (SMALLPOX)

A ni lati duro fun ọsẹ kan lẹhin Ibupa Ilẹẹgbona ki a to jade gẹgẹ bi eto ti apa keji Iwe ẹri Apa-bibu (Internation Certificate) pe Bupa-bupa (Vaccinating Officer) na ni lati yẹ ibiti a gbe ṣe ibupa na wo ni ọjọ karun titi di ọjọ keje lẹhin ibupa na Akoko ti Iwe-ẹri (Certificate) na wa fun ko kọja ọdun mẹta si akoko ti a kọ ọ.

Ti o ba ṣe pe nipa ti Apa-titun-bu ni, ero idalẹ na ni lati wa sọ fun Bupa-bupa (Vaccinating Officer) na ni ọjọ keji ti o ba ti bupa na.

Ni Health Office, Broad Street Lagos ni awọn ti o ba wa ni Eko ni lati ma a wa fun apa-bibu ti wọn ni arin agogo mejọ arọ ati agogo mejila ọsan lojojumọ (afi ọjọ ọsẹ nikan) ati ni Port Health Office, Lagos, ni arin agogo mejọ arọ ati agogo mẹwa ni ojojumọ (afi ọjọ ọsẹ nikan).

## APA-BIBU FUN ARUN MIRAN

Ni ti apa-bibu fun arun Onigbameji (Cholera) Akọ-iba (Typrhus) ati Ajakalẹarun (Plague) a ni lati lọ bere lọwọ Patgologist i/c Pathology Department, Lagos (Tel. Lagos 332) tabi ki o kọwe si eyikeyi ninu awọn Senior Medical Officer.

**Director Of Medical Services.**


## IKỌ LEWU




Nigbakugba ti o ba wukọ inira ni o jẹ fun ifun rẹ, ọkan rẹ yio si ṣiṣẹ kọja ala. Lo VENO'S COUGH MIXTURE lati da ikọ rẹ duro! Egbogi pataki yi ni gbogbo aiye mọ, o nda ikọ duro, o njẹ ki mimi rọrun, o mu ọgbẹ ọna ọfun kuro, o si ntọju ifun daradara.

Ra igo kan nisisiyi!

Egbogi to gbọ orişirişi ikọ, orişirişi otutu ti işe agba tabi ọmọde.

**VENO'S**
*LIGHTNING*
**COUGH MIXTURE**

## GBỌN IRORA NA KURO
( ELEYI NI ỌNA T'OYA T'OSIRỌRUN )



# MENTHOLATUM



"Mentholetum" Fifiparà a ma a mu ara didun aşi irora kuro werewere bi idan. Iwọ yio mọ atura rẹ lara, itura yio de lesẹkanna ti o ba ti fi pa ibi ti o ndun ẹ. "Mentholatum" ko nira rara lati lo, Iwọ şa şi fi pa ibiti o dun ẹ, Fipa ibẹ gan an, irora yio si lọ. Ohun gan an ti o gbọdọ şe ni yẹn, Irora aşi itura na yio yio si lọ. Bi Iwọ ba ti tete lọ ra "Mentholatum" itura na yio si de si ẹ. Lọ tete ra idẹ (jar) tabi agolo "Mentholatum" kan loni.

Bere fun Mentholatum gan an. Eyiti o jẹ pe awọn Mentholatum Co Ltd (Est, 1819) Slough, England nikan ni nwọn nşe e.

# J. A. Ajao & Brothers

GENERAL MERCHANTS
10, Egerton Road, Lagos, Nigeria

A nta awọn nkan wọnyi:— Işana orişirişi (Matches), Oogun Iyagbẹ, (Epsom Salt), Kafura Pẹlẹbẹ (Camphor), Atike (Face Powder), Ọti Didun (Mineral Water), Cement, Bata Funfun (White Canvas Shoes Leather Shoes (orişirişi), Beer, Shnapps, Gin, Wine, Brandy.

## Medicine Stores

A tun nta awọn orişirişi ògun ni oke Şọbu wa — Oogun Narun Iba, Atun-ẹjẹ-şe, Ikọ̀, Jẹdi-jẹdi, ati ògun fun Obinrin ati Ọkunrin Lakuregbe, Ehin Ọmọde.


NO. 446.

# NOTICE

## LOSS OF LICENCE FORMS

It is hereby notified that the undermentioned unused Licence forms have been reported lost from the office of the sub Treasurer Enugu

These Licence forms are hereby cancelled. Any Licence purporting to be issued on such forms are unauthorized and give to the person to whom they may be issued no rights, nor can they be accepted as evidence of the discharge of any liability

Any person who comes into possession of any of the undermentioned forms or is able to furnish any information relating to them should report the facts to the nearest police station.

Particulars of forms :-
Counterfoils Nos: 8301 8350 from Residents
Non-Native Licence Books Nos. 218/219.

H R HIRST
ACCOUNTANT—GENERAL

